# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 581 THURSDAY APRIL, 16 1964 (2D)


## Baba kan Ṣeesi Ta Ọmọ rẹ Nibọn

ABẸOKUTA:- Gbogbo enia bẹrẹsi sare ọlọmọgbọmọpọn pẹlu on idaamu nla nigbati awọn egungun kan npidan ni abuleko kan, ti nwọn npe ni Akindeleti o jinna pupọ si Abẹokuta ti nwọn si gbọ ariwo ọmọkunrin kan, ẹni ọdun mejidinlọgbọn ti o kigbe "oro o!" nigbati baba rẹ tabọn ti ibọn si ba ọmọ na ni ọjọ iṣẹgun ti ise ọjọ kẹrinla oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn enia ti o wa ni agbegbe na ati lati Abẹokuta ni nwọn wa woran awọn egungun ti nwọn npidan na.

Nigbati awọn enia na nho gee! ti nwọn si npatẹwọ bi awọn egungun na ti npidan orişişişi, ti inu wọn si ndun, lojiji ni nwọn gbọ iro ibọn kan ti o dun ninu igbo ti nwọn si tun gbọ ti Ọdọmọkunrin kan tun kigbe.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na ba tuka nibi iran egungun ti nwọn nwo lẹsẹkẹsẹ ni awọn "ara ọrun" di ara aiye nigbati awọn egungun na bọ aṣọ lori lati ri ohun ti o ṣẹlẹ.

Awọn ọlọpa si gbe oku ọkunrin na lọ si Ile-iwosan lakulaka Abẹokuta fun ayẹwo, nwọn si ti mu baba na ti o seeşi ta ọmọ rẹ nibọn. A lero pe baba na yio fara han niwaju adajọ ni owurọ yi.

# SANGBA FỌ! AWO YA MỌ DỌKITA MAJA L'ORI!

EKO:— Gbẹgẹdẹ gbina ninu Ile-ẹjọ gigajulọ ni owurọ ana nigbati Ọgbẹni Victor Durand Agbẹjọro Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ sọ niwaju awọn Adajọ pe, Dọkita Ọladipọ Maja lo gbero lati ko awọn ohun ọṣẹ wọlu ki işe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ gẹgẹbi Adajọ Agba Ile—ẹjọ giga Ọgbẹni Ṣowẹmimọ ti şe wi ninu idajọ rẹ.

Ọgbẹni Durand wa rọ adajọ pe ki nwọn o lọ wo ẹjọ ti Dọkita Maja funra ara rẹ ro niwaju adajọ, nibi ti o ti sọ wipe on lọ si Ghana lati lọ ra awọn ohun ọṣẹ.

O tun se alaye pe ẹda iwe owo ẹgba a pọnun (£2,000) ti Dokita Maja mu lọ si Ghana ki işe oloye Awolọwọ lo fun Maja ni owo na gẹgẹ bi nwọn ti şe wi, Jakande ni o fun ni owo na, ki isi şe lati fi ra ohun ọṣẹ bi ko şe lati fun awọn enia ti o mba "Allied Newspapers" ta Iwe Irohin wọn ni Ghana. Lẹhinna nwọn mu iwe owo na jade awọn adajọ si yẹwo.

O tun sọ fun adajọ pe lẹhin ti nwọn fi owo na ran Dokita Maja ni iwe kan de si ọdọ Oloye Awolọwọ ti Ọgbẹni S. Ikoku sọ pe Maja ko fun on ni owo. Nwọn mu lẹta na jade awọn adajọ gba lẹta na, Ọgbẹni Brett, ọkan ninu awọn adajọ rerin o si kọ nkan silẹ ninu iwe rẹ.

Ọgbẹni Durand ni Dokita Maja sọ fun Ibrahim Immam, ti işe Aşiwaju ẹgbẹ UMBC ni Ipinlẹ Ariwa pe, on fẹ ko awọn ohun ọṣẹ wa si Ipinlẹ Ariwa on yio si tun fun Immam ni owo şugbọn Immam sọ pe "Owo ni mo fẹ nko fẹ ohun ọṣẹ"

O tun şe alaye pe Dokita Maja sọ fun Ibrahim Immam pe nigbati on lọ si Ghana nipa işẹ ara on, on gbi yanju lati ko awọn ohun ọṣẹ ti on ra wale ninu apo ẹja panla; şugbọn on ko le ko wọn wa le nitoripe ara nfu on, on si pada wale.

O tun şe alaye pe Dokita Maja tun nşe işẹ owo kan ni Abẹokuta. Ọgbẹni Durand wa pe akiyesi awọn adajọ si ẹjọ ti Ọgbẹni Onipẹde ro niwaju adajọ Ṣowẹmimọ pe, Dọkita Maja da Ile işẹ kan silẹ ni Lafẹnwa şugbọn o ti ti Ile işẹ na ki o to di asiko ti nwọn nşe ẹjọ na.



Lateef Jakande

Şugbọn o ya enia lẹnu pe Ọgbẹni Onipẹde ko darukọ iru işẹ na ti Dọkita Maja da silẹ ni Lafẹnwa.

O tun şe alaye pe, iru Dọkita Ọladipọ Maja ko yẹ ni ẹniti Ijọba gbọdọ fi silẹ laifarakọrin, o ni eyi ya enia lẹnu kọja iruju.

Ọgbẹni Durand tun rọ awọn adajọ lati lọ wo ẹjọ ti Immam ro niwaju Adajọ pe, Dọkita Maja sọ fun on pe, ni ọjọ kan nigbati awọn ọmọ Ile Igbimọ Aşofin Apapọ Ijọba wa ninu ipade ni on (Dọkita Maja) yio lọ rọ agba lu Ile Igbimọ ti awọn enia inu rẹ yio si şegbe.

O ni, nigbati nwọn bere lọwọ Immam, o da wọn lohun ninu ibere rẹ pe Dokita Maja sọ fun on pe on yio fọ Ile Igbimọ na ni ọjọ kan, şugbọn ko darukọ ọjọ kan pato ti yio şe işẹ na, bẹni ko si sọ fun on pe ẹgbẹ Afẹnifẹre lọ ran on wa si Oke-Ọya.

Bi o ti sọ ọrọ yi tan ni Ọlọla Vahe Bairaimian rẹrin musẹ lori aga ijoko nigbati Durand sọ fun adajọ pe "ẹ lọ wo ọrọ na ni oju kọkanlelogoji (Page 41).

O tun şe alaye fun Ile ẹjọ pe Ọgbẹni Dokotri ti o wa jẹri ni Ile ẹjọ ki işe ẹlẹri ododo, nitoripe ni asiko ti o wa jẹri ni Ile ẹjọ; ẹgbẹ UMBC ti o ti mba (A. G.) şepọ ti kuro lẹhin (A. G.) ni asiko na nwọn si nwa ọna lati ba ẹgbẹ N.P.C. şe pọ.



Oloye Awolọwọ

Ninu ipade ti nwọn şe ni Kaduna ni asiko na nibiti nwọn ti nşe eto lati dapọmọ ẹgbẹ N. P. C. o ni enia mẹrin lo wa şe aşoju ẹgbẹ N. P. C ninu ipade na Alhaji Pategi ati Alhaji Ahmadu Bello pẹlu awọn enia meji miran pẹlu wọn.

O wa şe alaye pe, awọn enia ti nwọn ti ni Oloye Awolọwọ sinu tẹlẹ ni Apapọ Ijọba pe lati ma a wa jẹri niwaju Ile ẹjọ "ọta ẹni ki isi pa odu ọya, a fi ọlọmọ polo."

Ọgbẹni Durand wa pe akiyesi awọn adajọ si ẹjọ ti Ọgbẹni Ṣowẹmimọ da pe, ki o to le şe idajọ, o tọ o si ye, ki o mọ iru iha ti awọn enia na kọ si ara wọn.



Immam Ibrahim

Nigbati ọlọla Taylor bere ọrọ kan lọwọ Durand, o dahun pe, "Nigbati Ijọba ti gbọ gbogbo ọrọ ti Dokita Maja sọ yi. o yẹ ki nwọn ti mu Dokita Maja lẹsẹkẹsẹ.

O tun şe alaye pe, ti adajọ ba le gba ọrọ ti Dokita Maja sọ gbọ o jẹ iyalẹnu pe ko gba ọrọ ti ẹgbe Afẹnifẹre o ninu ipade wọn gbọ Ko si ẹjọ niwaju idajọ ti o le mu enia gbagbọ pe Oloye Awolọwọ fi owo ranşe si Ọgbẹni Ikoku ni Ghana, gẹgẹbi iwe ti o wa niwaju awọn ati akọsilẹ inu iwe na.

O ni, nigbati Oloye Awolọwọ wa ni Ikoyi l'Eko ti awọn enia kan si sọ pe nwọn ri nkan ni Ikẹnnẹ ilu ti o jinna si Eko ni nkan bi adọta ibuso (50 miles).

O tun pe akiyesi awọn adajọ si Ọrọ ti Immam sọ pe, ninu Ọdun 1961 ni Dokita Maje wa ba on ni

WO OJU EWEẸKFA

# IṢẸ AWỌN ỌBA ILẸ YORUBA LARIN WA

Ni ilẹ Yoruba laiye atijọ ọba ni a ka si bi igbakeji Ọlọrun to bẹ ti aba nba tabi ki i lorukọ a n a sọpe, Kabıyesi, Alaiye, Kẹge lori aiye; igbakeji orişa. Laiye igba na ọmọde ko to lati wo oju ọba rara.

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye, Eko

Ọdọ ati obinrin ni ilu miran ni ilẹ Yoruba a ma boju wọn tabi ki nwọn doju bolẹ nigbati ọba ba nkọja ni ọna wọn. Kiki awọn oloye nla lo le sun mọ ọba ti nwọn si le wo oju ọba nigba na. Awọn ọba papa ki ri ara wọn, melomelo ki nwọn si ma wo ara wọn loju.

Fun idi eyi awa ti a mọ



Ọba Adesanya
Ọdẹmọ ti Ishara

diẹ ninu awọn ọba wọnyi ti a si mọ riri ipo nwọn. O şoro pupọ fun wa lati mu kalamu wa lode oni lati sọrọ kan lodi si wọn.

Nitori ẹni ami ororo Oluwa ni a ka wọn si ni ilẹ Yoruba eyi ti işe ilẹ Oduduwa ẹni ikẹ, ọwọ, ilẹ Yoruba.

AIDỌGBA

Şugbọn lode oni, bi nkan ti nlọ si ti iwa ọlaju ti ko fi ọwọ fun awọn ọba wa tabi iwa ọlaju ti de ti awọn ọba wa papa ti sọ ọla wọ nu lai mọ idi ohun ti nwọn tẹle nipa bayi iwa aidọgba de si orilẹ wa.

Ohun pataki to mu mi kọ iwe yi loni ni awọn iwa aimọ pupọ ti awọn ọba wa ntẹle ni reti pe nwọn nhu iwa ẹtọ ati ẹyẹ fun idagbasoke ilẹ Yoruba.

Fun nkan bi ọdun kan to kọja, Ija kan bẹ silẹ ni Iwọ-Orun. Ninu rogbodiyan yi ni awọn ọba wa sare wa ba Alakoso Ijọba Apapọ ilẹ Nigeria ni Eko.

Lẹkansi lai pẹyi awọn ọba lati Iwọ-Orun tun lakaka lati wa ri Alakoso Ijọba Apapọ Nigeria fun wipe a yọ Mr. Alade fun awọn iwa aidọgba pe Mr. Alade ti ohun ikọkọ Ijọba Railway han si ibi ti nwọn ro pe ko tọ si i.

Ki şe ohun to dara wipe ohun Ikọkọ tabi ohun Ipamọ ibi işẹ Ijọba nbọ si ode. Nigba miran Yoruba a ma pe Iru iwa bẹ ni iwa Ofofo.

Ti a ba si fi ẹsun ofofo tabi iwa opurọ şun ọmọ ẹni, Mo ro pe ohun to dara julọ ni ki a jẹ ki ọmọ na ro ẹjọ tirẹ fun aiye gbọ.

Ti iladi ọrọ na ko ba dara to tabi ti nwọn ko ba gba iladi ọrọ, mo ro pe aye tun wa lati gbe lọ si ibi miran to tun ga ju lọ.

Ninu ọgbọn Yoruba to wipe a ki ni enia, lori igi ọsan ki-a ma tun ma mu aipọn ọsan.

Fun awọn ọba emi ko yọda tabi gba fun wọn pe ki nwọn tun fi ori ilẹ wọn silẹ lati ma wa ri Alakoso Ọlọla Abubakar.

Nwọn le wa fun nkan pataki to ju iyẹn lọ ki işe fun ti Mr. Alade.

Kini awọn oşelu to wa ni Ile Igbimọ ti Iwọ Orun nşe fun owo tabuwa ti nwọn ngba fun itọju ilẹ Yoruba?

Fun awọn ọba wa lati ma yan ikọ wa si ọdọ Alakoso Ijọba Apapọ nigbati ọrọ ko de oju rẹ ko ba eti inu rara.

Iru irin ba wọnyi ko le fun nwọn ni ọla ti o yẹ fun wọn rara. nigba melo ni a tilẹ gbọ pe awọn Ẹmir kan ni oke Ariwa yan ikọ wa ba Alakoso Ijọba Apapọ.

Tabi igba melo ni obi kan yan ikọ kan wa si Eko fun ayẹwo ọrọ kan niwaju Ijọba Eko?

Ọgbọn mi ko to lati mọ idi ti awọn ọba wa ni lati ma fi ara wọn wọle fun işẹ ikọ lọ si ibi han. Ikọ miran ki şe işẹ awọn ọba wa rara.

Lẹhin na iru ọna ti awọn ba wa ngba ni ọna ẹgbẹ oşelu. Nigba pupọ ni awọn Oaju oşelu nkilọ fun awọn aşba pe ki nwọn ma şe yọ ọnu si ọrọ ilu (Politic) şişe.

Ki işe pe wọn ọba ko le dabun si ọrọ Ilu şişe kọ. Şugbọn lati fi ade ori wọn silẹ ninu iyara ki nwọn ma şe ahesọ si ọrọ ti ko kan wọn rara eyi ko dara to nitori ba gbogbo ilu ni ọba jẹ ko yẹ ki o fẹ ẹnikan yatọ si ẹnikan nitori ọmọ ko ni ayọle ẹni ti ọmọ sin lo bimọ.

Bẹ gẹgẹ ni ọrọ awọn onşelu, ko si ẹgbẹ oşelu to şe gbẹkẹle titi lọ. Bi



S. O. Jaiye
Onigegewura

ago ti nyi kiri ni iwa inu awọn oşelu nyi kiri.

BATA IDẸ

Fun ọba ti ko ba fẹ ki bata idẹ ẹsẹ on wọ omi ti ko si fẹ ki ẹrẹ ta si aşọ igunwa to wọ sọrun.

Ati ki ade oni to jẹ ogo ki o si kuro lori rẹ O dara ki ọba takete si ọrọ ilu sişe ti ki işe ti wọn.

Jẹ kin mu ọrọ yi wa si iranti awọn ọba Iwọ-Orun oni yi pe; lati igba ti ati le Alafin Ọyọ ati arẹmọ rẹ kuro lori Itẹ lai si atunşe ati ironupiwada fun imupadabọ eto Arẹmọ pada bọ si Ọyọ emi ko iti ri isinmi kan larin ọba wa

Emi ki işe woli şugbọn



Ọba Adesọji Aderẹmi
Ọni ti Ife

ẹri ọkan nsọ fun mi pe o yẹ ki awọn ọmọ alade ilẹ Yoruba şe apero lori ọrọ aidọgba wọn. Mo sọ eyi fun awọn ọba bi nianti wọn. Riro di ọwọ wọn fun amuşẹ.

Paripari ọrọ kekere yi ti awọn ọba wa ni ilẹ Yoruba ba fẹ ilọsiwaju ilẹ yi, gbogbo wọn ni lati şe ara wọn ni iti kan.

Lẹhin na ti gbogbo ọba Ẹmin ati ti şe awọn oloye nla wa o yẹ lati igba yi lọ ki nwọn lọ wa ọna ti nwọn yio ma şe apero kan fun idagbosoke Ilẹ gbogbo Naijiria.

Aiye ti a wa loni ki işe aiye ti ao ma sọ pe eyi ni ẹkun ilẹ mi nikan tabi eyi ki işe ti emi.

Gẹgẹ bi ọgbọn Yoruba ti o sọ pe agbajọ ọwọ ni a fi sọ aya. Nitori na ki awọn ọba jọwọ lori ọrọ mi yi.

Ti nwọn ba şe nkan wọnyi mo ro pe ade wọn yo pẹ lori bẹni bata ko ni gbo lẹsẹ wọn.

Ijọba nwọn yio si ma dun yungba bi ti aiye Ọba Abiọdun lode Ọyọ. Oluwa a jẹ ki aiye nyin toro o.

# IWE SI OLOTU

## Ọlọla Balewa Ẹ Ranwa Lọwọ

Olotu ẹ dakun e gba mi ni aye lati ba Alakoso Ijọba Naijiria Ọlọla Abubakar Tafawa Balewa ati Minista fun ero ise *Lebira* J M. J. Johnson pe, ki nwọn lo ipo rere wọn lati ri wipe awọn o ṣiṣẹ gba owc wọn ni bl og njọ oṣu yi nitori awọn Musulumi ti yio ra ẹran Ileya.

O dabi enipe ti ọdun Nusulumi ba *ti* de awọn Ijọba *ki* ka *si* rara, nwọn *ko* ile pe ni nkan gi di. *Bi* o se ọdun awọn ẹlẹsin keji wa ni nwọn yio san owo ni asi*ko* nwọn yio se gbogbo rẹ foda foda,

Mo si bẹ awọn enia dudu ti nwọn da iṣẹ silẹ pe, ki nwọn ṣe anu awọn oṣiṣẹ nwọn, ki nwọn san owo wọn ki ato ṣe Ileya.

Bẹ na *ni* mo tun be awọn oyinbo onṣowo ki nwọn ma fi iya je ọmọ ọlọmọ ki nwọn san owo oṣu fun awọn oṣiṣẹ nwọn ki a to ṣe Ileya.

Ọpọlọpọ ni ofẹ lọ ri awọn ara rẹ ọpọlọpọ ni ofẹ ṣe inawo ọdun



Alhaji Abubaka Tafawa Balewa
Alakoso Ijọba Apapọ Ilẹ Niajiria

eya bi nwọn ba gba owo ni pari oṣu ki o ba nawo ti Ileya mu.

Gẹgẹbi inawo ọdun Ileya ti mo mọ Musul*u*mi ododo gbọdọ ra ẹran abiwo ganganran ti o si rẹwa ti osi fun yo dada.

Adupẹ

Emi ni
Hadji Y. A Disu

Eko

## E Ku Iṣẹ O

Olotu awa *o*nkawe nyin *o*loyin mọmọ Irohin Imọlẹ dupẹ pupọ lọwọ nyin ati aw*ọ*n oṣiṣẹ nyin pẹ*l*u fun itan *i*lu Ijẹbu-Igbo ti o *j*ade ninu iwe nyin laipẹ yi.

A si tun dupẹ gidigidi fun iwe nyin ti o ma nde ọwọ wa nigba gbogbo ni ilu Ijẹbu-Igbo awa onkawe nyin si ngbadun iwe Irohin Imọle pupọ fun awọn itan orisirisi ti o ma *n*jade *n*inu iwe na papa julọ fun irohin oloyinmọmọ ti anri ka ninu iwe na.

Inu wa yio du*n* pupọ ti awọn iye iwe Irohin Imọlẹ ti nwọn ma nko wa si Ijẹ*bu*-Igbo ba le pọ ju bẹlọ ati pe ọpọlọpọ enia lo nfẹ ma *a* ka iwe na.

Awa onkawe nyin si tun nfẹ ọrọ lati ẹnu Yẹyẹnat*u* oniyẹye Eko laipẹ yi.

Mo dupẹ o, Olotu ọkọ Ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Em*i* ni
JOSEPH ỌRẸKỌYA
Ij*ẹ*bu-Igbo

## Ẹ ba Wa Moju To Ele Yi

Olotu inu mi yio dun bi eba le gba mi ni aye lati ke si awọn Ọlọpa lati le ba wa mojuto awọn oni mọto akero ti nko ero l*a*ti Shomolu wa si Eko, papa awọn to nwa awọn mọto ti nwọn npe ni "bọle kaja".

Eyi to si jẹ Ohun ti awọn Ọlọpa yio ba awa ero ti nwọ inu awọn moto na ṣe ni lati ma le abojuto awọn Direba na.

Awọn mọto ti ko gbọdọ gba ju enia me*j*ile logbọn lọ nwọn yio fi ko ero to Ogogi tabi ju lọ ati pe ara ti awọn oni moto na ma nsa si ti po ju.

Inu awa ero to nwọ inu awọn mọto na yio dun bi awọn Ọlọpa ba le da wa ṣe amojuto awọn "digbolugi" dirẹba wọnyi,

Olotu, mo dupẹ aiye ti ẹ gba mi Okọ Ọba ko ni ṣa nyin lese o.

Emi ni
ANTHONY ADEBOYEJO
Shomolu.

## A Nfẹ Iwe Irohin Imọlẹ

Olotu, inu wa yio dun bi ẹ ba le jẹ ki a ma ri iwe *n*yin oloyinmọmọ Irohin Imọlẹ nigbagbogbo ni ilu Ọwọ. Iwe na dun mọ wa lati le ma ka lojojumọ gẹgẹbi awọn ilu yoku.

Eyi yio dun mọ wa bi ẹ ba le ba awọn oṣiṣẹ nyin sọrọ gẹgẹbi awọn yio ṣe ma a *j*ẹ ki Irohin Imọlẹ ma to awa onkawe nyin lọwọ.

Awa si mọ pe gedegbe ni Irohin Imọlẹ wa ati pe lẹ kọkan ti i*we* na ma nde ọdọ wa ni a si ngbadun iwe *na*.

Inu wa yio dun bi ẹ ba le yan aṣoju kan si ilu Ọwọ lati jẹki a ma ri iwe na nigbagbogbo.

Ọpọlọpọ itan ilu wa ti a nfẹ sọ sinu iwe Irohin na ti a ko mọ gẹgẹbi yio ṣe de ọwọ nyin ki nwọn ba le tẹ jade,

Awa o nkawe ny*i*n si ro pe bi ẹ ba ni aṣoju ni ilu wa yio jẹ ohun pataki fun wa lati le ma fi itan na *r*anṣẹ si nyin.

Ẹ ku iṣẹ o, ajinde ara yio ma jẹ.

Emi ni,
ADEKOLA AMỌO,

Ọwọ


# Kere o

10TH BOOK OF MOSES: Iwe kẹwa Mose, Iranlọwọ nla fun awọn Ẹgbẹ Aladura lọna iwaa... ifihan, asọtẹlẹ. Aṣiri imularada lọna orişirişi, aşiri isọ agan di ọlọmọ, igba ni lọwọ awọn agbaalagba. Agbojọ, ki a wi bẹẹ ki o si ri bẹẹ lọnakan, mayehun atata. Pọnun kan (£1) pere. A le ri i ra lọ dọ MANAGER 15, Araoti Street, Yaba-Nigeria ati ni ọdọ awọn wọnyi: Abudu Akangbe, Ile Tabintin, Ikire via Ibadan, David Taiw., 19, Ajegunlẹ Street, Ilupeju, Mushin ati Thomas A k i n k u n m i, c/o-Dr Ayọ Alade, Oke Elerin, Ogbomọsho.



# Congreve,s Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi tituṅ fun gbogbo awọn Obinrin ti o be ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ekọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi – oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfọri abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirisi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni ia nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orişirişi rọbirọki egbogi ti wọn ko wa nisisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ aju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ila-itọ tabi se iwosan iyọuu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirisi omira pẹlu wọn mbẹ ni şọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone: 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji)



BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

UN

Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku

ATI

## Iwe Igbeyawo

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TỌ AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# Lọya Adeoye De Lati Londọnu

EKO:- Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Ọgbẹni Adebisi Ọnaọlapọ Adeoye ti o ti lọ Londọnu ba ọkọ-elefin gunlẹ si ebute ọkọ l'ẹhingbẹti lẹhin ti o ti yege ninu ẹkọṣẹ Agbẹjọro (Lọya). Nkan bi ọdun mẹrin o ṣe ni Londọnu.

Ọmọ ılu Esiẹ ni Ọgbẹni A. O. Adeoye. Alhaji Y. A. Disu (Hadji Awaiye-waṣere) ni Olotọ rẹ. Dọkita T. O. Elios si ni onimọran laisi rẹ, ki o to lọ Londọnu ọmọ Ọgbẹni Albert Adeoye si ni Lọya na.

Ero pọ bi omi ti o lọ yọ pade rẹ. Ẹsẹ awọn ọmọ ilu Esiẹ ti o wa l'Eko pe ṣọṣọ si Ebute-ọkọ na ati si ile baba ọmọ na ọjọ na.

Ajẹt ati amuti si ni nwọn fi onjẹ ati ọti oriṣiriṣi ṣe lẹhin ti nwọn ti lọ ṣe akanṣe isin ati idupẹ Oore fun Ọlọrun ni Ṣọọṣi Ọba l'ẹnu-Ọwa.

Ẹni rẹ ni Lọya na, o ni iwa rẹlẹ, o ni laakaye pupọ, o ni mọ ọrọ sọ pupọ, o si yara pupọ. Ki Ọlọrun fi ibukun si iṣẹ rẹ. o

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS (Jan 21–Feb 18) Ṣọra! nitori ọkan rẹ yio bẹrẹ si ro irokuro ohun to dara fun ọ ni wipe, ki o lọ sun orun diẹ. Pa ẹnu rẹ mọ ki şe gbogbo enia lo ma fi aşiri rẹ han fun

PISCES (Feb 19–Mar 20) Ṣe pẹlẹpẹlẹ bi o ba rin irin ajo loni, ki o ma ba fi ẹmi ara rẹ wewu. Lakọkọ ti o ba bẹrẹ irin ajo, na nṣe ni yio dara mọrọnyin-mọrọnyin, ṣugbọn ıgbẹhin nkọ?

ARIES (Mar 21-Apl 20) Ọgbọn ori rẹ yio ko ire ati anfani pupọ wa ba ọ bi o ba le ṣe pẹlẹpẹlẹ. Tọju aisan ara rẹ ati nipa sisọrọ te mu ọgbọn dani, iwọ yio ṣe orire loni

TAURUS (Apl 21-May 21) Amodi kan yio ṣẹlẹ si ọ ni akoko owurọ yi nitorina ki o ṣe tọju ara rẹ. fi ara silẹ, ki o si sun orun diẹ.

GEMINI (May. 22–Jun. 21) Ohun kan yio sẹlẹ si ọ, yala ni rere tabi ni buburu ni akoko owurọ. Gbogbo ohun ti o ba si fẹ ṣe, jẹki o jẹ ọjọre, ki o si feti si ımọran ti nwọn ba da fun ọ.

CANCER (Jun, 22–July 22) Ṣọra nipa orikunkun ti o nṣe, mase fi aye silẹ fun agidi ọkan rẹ. pẹlupẹlu ara rẹ nfẹ itọju daradara sọra ki o maṣe ba ẹnikan jiyan ọrọ kan maṣe fọkan sibẹ rara.

LEO (July 23-Aug. 23) Oru yio mu ọ pupọ loni, o si le fa amodi wa pẹlu. Maşe kanra, ki o si şe jẹjẹ, ki amodi na ma ba pọju.

VIRGO (Aug. 24–Sept. 23) Iwọ yio ba wọn sọrọ ajọsọ kan, eyiti yio ṣe ọ ni anfani, ki o si ṣe akiyesi ọrọ ti nwọn ba mba ọ sọ, ki o si dahun si eyiti o ba kan ọ nibẹ.

LIBRA (Sept 24 - Oct. 23) Ọwọ rẹ yio tẹ ohun kan ti o ti jẹ eyiti o fẹ maṣe jẹki nkan ki nkan di ọ lọwọ lati ṣe eyi ti o tọ nitẹ.

SCORPIO (Oct. 24 - Nov. 22) Ronu wo daradara ki o to dawọle ohun kan lati ṣe Bi ọwọ rẹ ba si tẹ ohun ti o fẹ, kọ iwa palapala silẹ.

SAGITTARIUS (No.V23 - Dec. 21) Ṣe ohun ti o ti ngbero lati ṣe, maṣe lo ọgbọn inu ara rẹ ki ọrọ na ma ba daru.

CAPRICORN (Dec. 22 – Jan. 20) Maşe dawọle işẹ ti o lewu ni akoko yi ki o ma ba ko abamọ, ki o si ṣọra rẹ nipa ohun jijẹ tabi atẹnujẹ.


# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"

MO JẸ RI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ

ikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubori gbogbo ẹda patapata" Amin'

## "WS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ... eyẹ ki o ni na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SITTU STREET
HIbadan

# Kere o!

Fun anifan gbogbo ẹnyin onişowo, Iwe Irohin Imọlẹ yio ṣe ipolowo awọn ọja nyin fun nyin ni ọsẹ kan gbako ki ọdun Ileya o to de ati lẹhin odun ki awọn onibara nyin le ba nyin ra ọja ti ọdun Ileya ti mbọ yi.

Awọn Aṣoju wa yio ma a lọ kakiri lati bere fun awọn ti o ba fẹ lati polowo ọja wọn ninu Iwe Irohin wa.

Owo pọọku ni a ngba, dan wa wo lẹkan ki o sri bi ajo rẹ yio ti ta to,Ijafara lewu o.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

# RICHALET

Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara eni. si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogb awọn Egbogi ti nwọn npe n TỌNIKI Ẹjẹ! ti nwọn si nt kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi,

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba awọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalap Egbogi-n Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didu tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogi kokoro buruku t o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu.

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

